


**Láti ọwọ́ Ààrẹ Henry B. Eyring**
Olùdámọ̀ràn Kínní nínú Àjọ Ààrẹ Ìkínní

# Àwọn Ebí Lè Wà Papọ̀ Títíláé

Agbára oyè àlùfáà láti so àwọn ẹbí pọ̀ fún ayérayé jẹ́ ọ̀kàn nínú àwọn ẹ̀bùn Ọlọ́run tí ó ga jùlọ. Gbogbo ẹni tí ó bá ní òye ti ètò ìgbàlà ńfi ojú sọ́nà fún ìbùkún pípé náà. Nínú àwọn ayẹyẹ dídìpọ̀ tí a ṣe nínú àwọn tẹmpílì tí a ti yà sí mímọ́ ti Ìjọ Jésù Krístì ti Àwọn Ènìyàn Mímọ́ Ọjọ́ Ìkẹhìn nìkan ni Ọlọ́run ti fúnni ní ìlérí pé a lè so àwọn ẹbí papọ̀ títíláé.

Àwọn kọ́kọ́rọ́ oyè àlùfáà tí ó jẹ́ kí èyí ṣeéṣe ní a múpadàbọ̀sípò sí orí ilẹ̀ ayé láti ọwọ́ wòlíì Èlíjàh si Joseph Smith nínú Tẹ́mpìlì Kirtland. Àwọn kọ́kọ́rọ́ oyè àlùfáà wọ̀nnì ni ó ti ńti ọwọ́ dọ́wọ́ nínú ìlà àìjá nípasẹ̀ àwọn wòlíì alààyè nínú Ìjọ Jésù Krístì ti Àwọn Ènìyàn Mímọ́ Ọjọ́ Ìkẹhìn títí di ọjọ́ òní.

Olùgbàlà nínú iṣẹ́ ìránṣẹ́ ti ayé ikú Rẹ̀ sọ nípa agbára láti fi èdìdì di àwọn ẹbí nínú àwọn ọ̀rọ̀ sí Pétérù, Àpóstélì Rẹ̀ tó dángájíá jùlọ, nígbàtí Ó sọ pé, "Lóótọ́ ni mo wí fún yín, Ohunkúhun tí ẹ̀yin bá dè ní ayé, a ó dè é ní ọ̀run: ohunkóhun tí ẹ̀yin bá sì tú ní ayé, a ó tú ù ní ọ̀run" (Matthew 18:18).

Nínú ìjọba sẹ̀lẹ́stíà nìkan náà ni a ti lè gbé nínú àwọn ẹbí títíláé. Níbẹ̀ a lè wà nínú àwọn ẹbí ní iwájú Bàbá wa Ọ̀run àti Olùgbàlà. Wòlíì Joseph Smith ṣe àpèjúwe ìrírí ìyanu náà ní ọ̀nà yí nínú Ẹ̀kọ́ àti àwọn Májẹ̀mú.

"Nígbàtí Olùgbàlà yíò yọ a ó rìi bí ó ṣe wà. A ó rìi pé ó jẹ́ ènìyàn kan bíi tiwa.

"Àti pé irú ìbákẹ́gbẹ́ èyí tí ó wà láàrin wa níbíyìí yíò wà láàrin wa níbẹ̀, àfi pé yíò jẹ́ pẹ̀lú ògo ayérayé, ògo èyí tí a kò gbádùn báyìí" (D&C 130:1–2).

Ìwé mímọ́ yìí dáa lábà pé a le fi ìgboyà fi ojú sí irú ọ̀ṣùwọ̀n ti ọ̀run nínú awọn àjọṣepọ̀ wa láàrin awọn ẹbí wa. A lè ṣè ìtọ́jú tí ó péye fún àwọn mọ̀lẹ́bí wa, tí wọ́n wà láàyè àti tí wọ́n ti kú, láti ṣe gbogbo ohun ti a lè ṣe láti fi àwọn ìlànà oyè àlùfáà fún wọn tí yíò so wá pọ̀ ní ọ̀run.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ lára yín, ọ̀dọ́ àti àgbà, ti ńṣe èyíinì. Ẹ ti wá orúkọ ti àwọn bàbáńlá àwọn ẹni ti kò tíì gbà àwọn ìlànà tí ó lè dí yín pọ̀ mọ́ wọn.

Ó fẹ́rẹ̀ jẹ́ gbogbo yín ni ẹ ní àwọn ìbátàn tí wọ́n wà láàyè tí a kò tíì fi èdìdì dì nínú àwọn ẹbí nípasẹ̀ agbára oyè àlùfáà. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ní àwọn ìbátàn tí wọ́n wà láàyè tí wọ́n ti gba àwọn ìlànà oyè àlùfáà ṣùgbọ́n tí wọn kò pa àwọn májẹ̀mú tí wọ́n ti ṣe pẹ̀lú Ọlọ́run mọ́. Ọlọ́run yíò bùkún yín tí ẹ̀yin yíò lè ṣè ìrànlọ́wọ́ láti nawọ́ jáde sí gbogbo àwọn ìbátan wọ̀nnì nínú ìgbàgbọ́. Ẹ ní ìlérí kan tí Olúwa ṣe sí àwọn ọmọ ẹ̀hìn Rẹ̀ tí ó lọ̀ mú àwọn ẹlòmíràn wá sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀:

"Àti pé ẹnikẹ́ni tí ó bá gbà yín, níbẹ̀ ni ẹ̀mí ó wà bákannáà, nítorí èmi yíò lọ ṣíwájú yín. "Èmi yíó wà ní ọwọ́ ọ̀tún yín àti ní ọwọ́ òsì, àti pé Ẹ̀mí mi yíó wà nínú àwọn ọkàn yín, àti pé àwọn ángẹ́lì mi rọ̀gbà yí i yín ká, láti gbé e yín sókè" (D&C 84:88).

Láti ojú fèrèsé ibi iṣẹ́ mi mo ńrí àwọn ìyàwó àti ọkọ àṣèṣègbéyàwó ní ojojúmọ́ tí wọ́n máa ńya àwòrán ní ààrín àwọn òdòdó ẹlẹ́wà àti àwọn orísun omi tí ó ńtu sókè. Ọkọ ìyàwó máa ńsábà gbé ìyàwó rẹ̀ sí ọwọ́ rẹ̀, bí ó tilẹ̀ jẹ́ fún títa ìgbésẹ̀ gẹ̀ẹ́gẹ̀ẹ́, nígbàtí ayàwòrán yíó ya àwọn àwòrán ìgbeyàwó. Ní ìgbàkugbà ti mo bá rí èyíinì, mo máa ńro ti àwọn tọkọ taya tí

mo ti mọ̀, awọn tí ní àìpé—ìgbà míràn ní kété lẹ́hìn ọjọ́ ìgbéyàwó wọn—tí wọ́n níláti gbé ara wọn ní àwọn ọ̀nà míràn nígbàtí ìgbé ayé bá di líle. A lè pàdánù àwọn iṣẹ́. A lè bí àwọn ọmọ pẹ̀lú àwọn ìpèníjà ńlá. Àìlera lè wá. Àti pé nígbànáà, àwọn ìhùwa ti ṣíṣe sí àwọn ẹlòmíràn gẹ́gẹ́bí a ti fẹ́ kí wọ́n ṣe sí wa—nígbàtí ó rọrùn—yíò mú wa jẹ́ akíkanjú ọkùnrin àti akínkanjú obìnrin ní àwọn ìgbà ìtiraka wọnnì nígbàtí ó ńgba púpọ̀ ju bí a ṣe rò pé a ní nínú wa.

A jẹ àwọn ẹbí wa ní gbèsè irú ìbálòpọ̀ tí a lè mú lọ̀ sí iwájú Ọlọ́run. A gbọ́dọ̀ tiraka láti máṣe muni bínú tàbí gba ọ̀rọ̀ sí ìbínú. A lè pinnu láti dáríjì kíákíá àti ní kíkún. A lè tiraka láti ṣe àwárí ìdùnnú ti àwọn ẹlòmíràn ju ti ara wa. A lè jẹ́ onínúrere nínú ọ̀rọ̀ sísọ wa. Bí a ṣe ńtiraka láti ṣe gbogbo àwọn ohun wọ̀nyí, à ó pe Ẹ̀mí Mímọ́ wá sínú àwọn ẹbí wa àti sínú ayé wa.

Ìdánilójú mi sí yín ni pé, pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ ti Olúwa àti pẹ̀lú ìronúpìwàdà ọkàn, a lè rí ìmọ́lẹ̀ firí ní ayé yí níti irú ìgbé ayé tí a fẹ́ ní títíláé. Bàbá Ọ̀run nífẹ́ wa. Ó fẹ́ kí a padà wá sí ọ̀dọ̀ Olùgbàlà Rẹ̀, nípa agbára Ètùtù Rẹ̀, mu kí ìyípadà tí a nílò láti ṣe nínú ọkàn wa ṣeéṣe ní ètò láti wọ inú awọn tẹ́mpìlì mímọ́, lati dá àwọn májẹ̀mú tí a lè pamọ́, àti pé ní àsìkò kí a gbé nínú àwọn ẹbí títíláé nínú ògo ti ilé sẹ̀lẹ́stíà—lẹ́ẹ̀kan si.

---

**Ẹ̀KỌ́ LÁTI INÚ Ọ̀RỌ̀ YÍ**

Bí ẹ ṣe ńṣe àbápín ẹ̀kọ́ ti ẹbí ayérayé yí, ẹ gbèrò ohun tí Alàgbà Richard G. Scott ti iyejú àwọn Àpóstélì Méjìlá ti sọ pé: "Máa wá láti fún àwọn ẹbí lókun nígbà gbogbo. Kọ́ni pẹ̀lú ìran nípa pàtàkì ṣíṣe ìfi èdìdì di àwọn ẹbí nínú tẹ́mpìlì. . . . Nígbàtí ẹ bá ní ìran àwọn ìlànà èdìdì ti tẹ́mpìlì, ẹ̀yin yíò ṣe ìrànwọ́ láti kọ́ ìjọba ti Ọlọ́run ní orí ilẹ̀ ayé" ("Mo Ti Fún un Yín ní Àpẹrẹ kan," *Liahona,* May 2014, 34). Báwo ni ẹ ṣe lè ran àwọn wọnni tí ẹ ńkọ́ lẹ́kọ́ láti mú ìran ní ipá pàtàkì ti fífi èdìdì dì nínú tẹ́mpìlì dàgbà sókè? Pe àwọn tí a kò tíì fi èdìdì dì láti sọ̀rọ̀ nípa àwọn ìgbésẹ̀ tí wọ́n lè gbé ṣíwájú ìlànà náà. Pe àwọn tí a ti fi èdìdì dì láti sọ̀rọ̀ bí wọ́n ṣe lè pà ìran ti ẹbí ayérayé wọn mọ́ àti ṣíṣe iṣẹ́ láti mú kí àwọn ìbáṣepọ̀ wọn dárasi pẹ̀lú ara wọn.

## Ọ̀DỌ́

### Ìsomọ́ Ayérayé sí Ẹbí Mi

**Láti ọwọ́ Laura Burton**

Nígbàtí a gbà mí tọ́ ní ọmọ ọdún mẹ́ta, ìyá tí ó bí mi gbà àṣeparí ètò àgbàtọ́ náà tí àwọn òbí mi bá faramọ́ láti jẹ́ kí ńṣe àwọn ìlànà Ìjọ lẹ́hìn tí mo bá pé ọmọ ọdún méjìlá. Ó rò pé mo nílò láti dàgbà tó láti yàn fún ara mi, ṣùgbọ́n ó ṣòro púpọ̀ láti dúró.

Bẹ́ẹ̀ni, ó ṣòrò láti rí ọ̀pọ̀lọpọ̀ lára àwọn ọ̀rẹ́ mi tí wọ́n ṣe ìrìbọmi nígbàtí wọ́n pé ọdún méjọ, ṣùgbọ́n ohun tí ó tún le jù ni mímọ̀ pé a kò lè fi èdìdì di mí pọ̀ pẹ̀lú àwọn òbí alágbàtọ́ mi àti àwọn ẹ̀gbọ́n mi marún títí tí emi ó fi di ẹni ọdún méjìlá. Ẹ̀rú bà mí pé ohun kan yíò ṣẹlẹ̀ sí mi àti pé a kò ní lè fi èdìdì dì mí pọ̀ pẹ̀lú wọn.

Bí ọjọ́ ìbí mi kejìla ṣe ńbọ̀, a bẹ̀rẹ̀ sí ṣe ètò fún ìrìbọmi mi àti ìfi èdìdì dì mí pọ̀ pẹlú ẹbí mi. Àwọn ẹbí mi jẹ́ kí ńyan tẹ́mpìlì nínú èyí tí a ó ti ṣe fífi èdìdì dì. Mo ńfìgbàgbogbo lérò pé Tẹ́mpìlì San Diego California ni ó lẹ́wà jù, nítorínáà gbogbo ẹbí mi faramọ láti wa ọkọ̀ lọ sí California fún fífi èdìdì náà dì.

Èmi kò lè dúró tó láti di ẹbí ayérayé kan pẹ̀lú àwọn òbí mi àti àwọn arákùnrin àti arábìnrin mi. Ní àkókò ìfi èdídì dì mi, mo ní ìmọ̀lọ́kàn Ẹ̀mí tó lágbára gidi tí ó le láti fi sí ọ̀rọ̀. Báyìí tí a ti fi èdídì dì mi mọ́ ẹbí mi, àwọn ìmọ̀lára ti ìdàmú ni a ti fi ìtùnú àti àláfíà rọ́pò, ní mímọ̀ pé èmi náà báyìí ti ní ìsopọ̀ ayérayé sí wọn.

*Olùkọ̀wé ńgbé ní Utah, USA*

## ÀWỌN ỌMỌDÉ

### Bíbojú wo Tẹ́mpìlì

Àarẹ Eyring ṣe àlàyé pé nítorí ti oyè àlùfáà, a ní àyè láti lọ sí tẹ́mpìlì láti fi èdìdì dì pẹ̀lú ẹbí wa fún ayérayé. Yàá tàbí wá àwòrán ti tẹ́mpìlì kan tí ó fẹ́ràn jù kí o sì fi pamọ́ sí ibi tí ìwọ yíò ti maa ríi lójojúmọ́. Ṣe títò lẹ́sẹẹ̀sẹ bí ìwọ yíò ṣe múrasílẹ̀ láti lọ sí tẹ́mpìlì níjọ́ kan.

© ọdún 2015 láti ọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. A tẹ̀ ẹ́ ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/14. Àṣẹ Ìyírọ̀padà: 6/14. Ìyírọ̀padà ti *First Presidency Message, June 2015.* Yoruba. 12586 779

# Àwọn ìhùwàsí ti Jésù Krístì: Ìwàrere

Ìgbàgbọ́, Ẹbí, Ìranlọ́wọ́

*Ẹ fi tàdúrà-tàdúrà ka ohun èlò yĩ kí ẹ sì wá lati mọ ohun ti ẹ ó ṣe àbápín rẹ̀. Báwo ni níní òye awọn ìhùwàsí àtọ̀runwá ti Olùgbàlà ṣe nmú ìgbàgbọ́ yin ninu Rẹ̀ pọ̀sii ati kí ẹ bùkún awọn tí ẹ nṣe ìṣọ́ lé lórí nipa ìbẹniwò kíkọ́ni? Fún ìwífúnni síi, lọ sí* ***reliefsociety.lds.org****.*

*Èyí ni apákan onírurú àwọn Ọ̀rọ̀ Ìbẹniwò Kíkọ́ni tí ó ńfi ìhùwàsí àtọ̀runwá ti Olùgbàlà hàn..*

"Jẹ́ kí ìwàrere ṣe àwọn èrò yín lọ́ṣọ́ láìsimi; nígbànáà ni ìgbẹ́kẹ̀lé yín yíò lágbára síi níwájú Ọlọ́run: àti pé ẹ̀kọ́ ìpìlẹ̀ ti oyè àlùfáà yíò kán lé ọkàn yín bí ìrì látì ọ̀run". (D&C 121:45).

Kíni ìwàrere jẹ́? Ààrẹ James E. Faust (1920–2007) sọ pé: "Ìwàrere ní kíkún òye rẹ̀ yíká gbogbo àwọn ète òdodo tí yíò ràn wá lọ́wọ́ láti ṣe bí ìwà wa yíò ti rí."[1] Ààrẹ Gordon B. Hinckley (1910–2008) ṣe àfikún: "Ìfẹ́ ti Ọlọ́run ni gbòngbò ti gbogbo ìwàrere, ti gbogbo ìdára, ti gbogbo okun ìhùwàsí."[2]

Nípa ti ìbáṣepọ̀ láàrín àwọn obìnrin àti ìwàrere, Alàgbà D. Todd Christofferson ti Iyejú Àwọn Àpóstélì Méjìlá sọ pé: "Àwọn obìnrin ti mú ìwàrere kan tí ó dájú pẹ̀lú wọn wá sínú ayé, ẹ̀bùn àtọ̀runwá kan tí ó ńmú wọn ṣe ọlọgbọ́n ní fífi irú ìwà bíi ìgbàgbọ́, ìgboyà, níní òye ìrírí ẹlòmíràn, àti àtúnṣe sínú ìbáṣepọ̀ àti sínú àwọn àṣà. . . .

"Ẹ̀yin arábìnrin, nínú gbogbo awọn ìbákẹ́gbẹ́ yín, ìbáṣepọ̀ yín pẹ̀lú Ọlọ́run, Bàbá yín Ọ̀run, ẹnití ó jẹ́ orísun agbára ìwà yín, ni ẹ gbọ́dọ̀ fi ìgbà gbogbo gbé ṣíwájú nínú ayé yín. Ẹ rántí pé agbára ti Jésù wá nípa ìfọkànsìn inú kan Rẹ̀ sí ìfẹ́ ti Bàbá. . . . Ẹ tiraka láti jẹ́ irú ọmọ ẹ̀hìn ti Bàbá àti Ọmọ, àti pé agbára yín kò ní ṣá láéláé."[3]

## Àfikún Àwọn Ìwé Mímọ́

Psalms 24:3–5; Philippi 4:8; 2 Peteru 1:3–5; Alma 31:5; D&C 38:23–24

## Láti inú Àwọn Ìwé Mímọ́

Lóní, àwọn obìnrin oníwàrere, tí wọ́n kún fún ìgbàgbọ́, nawọ́ jáde sí Olùgbàlà. Ní Lúkù 8 a kà nípa obìnrin kan tí ó ní ìsun ẹ̀jẹ̀ fún ọdún méjìlá tí kò lè ní ìwòsàn. Ó ńwá ìwòsàn nígbàtí ó "wá sí ẹ̀hìn [Krístì], ó sì fi ọwọ́ kan ìṣétí aṣọ rẹ̀: lójúkannáà ni ìsun ẹ̀jẹ̀ náà [dúró]. . . . Jésù sì wípé, Ẹnìkan ti fi ọwọ́ kàn mi: nítorí mo wòye pé agbára[4] ti kúrò lára mi Obìnrin oníwàrere yí wólẹ̀ níwájú Rẹ̀, ó sọ fún "níwájú gbogbo ènìyàn" pé "òun ló fọwọ́kàn án" ó sì ní ìwòsàn lójúkannáà. Ó sì wí fún pé, Ọmọbìnrin, tújúká, ìgbàgbọ́ rẹ mú ọ lára dá" (rí Luke 8:43–48; wo 6:17–19) bákannáà.

Nípasẹ̀ ìwàrere Rẹ̀,[5] Krístì lè wòsàn, lè múni ṣe ohunkóhun, fún ni lókun, tùni nínú, àti dun ni ninú nígbàtí a bá yàn pẹ̀lú ìgboyà àti ìgbàgbọ́ láti nawọ́ jáde sí I.

### ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁŃPẸ́

1. James E. Faust, "Ìwàrere ti Àwọn Ọmọbìnrin Olódodo ti Ọlọ́run," *Liahona,* May 2003, 108.
2. Gordon B. Hinckley, "Àwọn Ọ̀rọ̀ tí a fà yọ nínú àwọn Ọ̀rọ̀ Ààrẹ Gordon B. Hinckley láìpẹ́," *Ensign,* Apr. 1996, 73.
3. D. Todd Christofferson, "Agbára Ìwà ti Àwọn Obìnrin," *Liahona,* Nov. 2013, 29, 31.
4. Ìwàrere ní agbára (wo Mark 5:30).
5. Nínú ìtọ́sọ́nà sí àwọn ìwé mímọ́, "Oyè àlùfáà" ni a túmọ̀ bíi: "Àṣẹ àti agbára tí Ọlọ́run fifún ọkùnrin láti ṣiṣẹ́ nínú ohun gbogbo fún ìgbàlà ti ọmọ ènìyàn" (D&C 50:26–27).

## Gbèrò Èyí

Báwo ni ìwàrere ṣe ńfún wa lágbára àti okun?

© ọdún 2015 láti ọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. À tẹ̀ẹ́jáde ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/14. Àṣẹ Ìyíròpadà: 6/14. Ìyíròpadà ti *Visiting Teaching Message, June 2015.* Yoruba. 12586 779